**Lemomu Jamiyu Ilorin di Ologbe**

Anu şeni g digidi lati jihin iku Lemomu Jamiyu Alufa Alhaji Salibu Ayinla ti işe olori gbogbo Lemomu Ilorin, o fi Omo m e j i l a sile. Olorun ko gba işe rę.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**GBANJO O!!**

Enyin A l a g b e d e (Gold smith) ati Fadaka (Silver smith) E sare wa ra Opoku-Qyoko "SILVER" E bere lodo :-

**Korede Store**
**108, Evans Street,**
**Lagos. Phone: 23336**

VOL. V No. 205 MONDAY MAY 8 — MAY 14 1961 KOBO KAN (1d)

## Okan tun de o! Agogo Adesına, Jesu Oyingbo ni ari ti a nwi,

# Samuel Oke-ri-orun Jesu Ibadan ni kilo subu te On

IROHIN TA SI WA LETI WIPE, L E H I N TI AWON OLOPA TI TE OWO JESU OYINGBO BO ASO TAN, NI JESU MIRAN TUN DIDE NI ADUGBO KAN TI WON N P E NI OKE BOLA NI A BA GBERASO, ODI IBADAN. NIGBATI ADE IBE NSE NI A BA OLORO, TI O WO ASO AGBADA ONIŞEDA TI O SI FE RAPATA SORI AGA. EYI NI ORO TI O ŞELE LARIN WA PELU RE, O WIPE, EMI OLORUN WA PELU ON, GBOGBO AWON TI O JOKO PELU RE NINU ILE NA SI NJERI RE PE BENI! DAJUDAJU ORUKO NI S. OKE-RI-ORUN

Mo ni agbara lati so abosi di olowo, mo le mu ki agan obinrin bimo, mo le mu ki enia di onipo giga lenu işe, ko si amudi ti nko le wo san.

Bi o ti pari oro re yi tan, gbogbo awon ti o wa lodo re, se Kabiyesi lati fi jeri si oro re, ki enia to ri Jesu Ibadan ba şoro, o ni lati mura l a t i fi i g a gbaga, o ni lati si fila, ki o bo bata ese re, ki o si şe aluwala. O fere jo wipe Jesu Ibadan yi le ju J e s u Oyingbo. Nitoripe nigbati awa Oniwe Irohin de i b e o şepe luwa o si şoro buruku si wa, tobe ti o je w i p e, bi ile ba ti su ni emi yio bere amudi. E n i kan wa so fun mi pe, ko nşe agbara re na lo po be, egbogi e p e kan ti o mu daui li o nlo. Nwon tun fi ye mi pe, ara ilu Ikirun ni Jesu Ibadan na nşe işe Isegun lo si ti nşe tele ri. Oro Jesu Ibaban na wa su mi loju nitoripe awon oniwe Irohin miran ti a jijo lo sibe nigbati o se pe fun wa nbe ni alafia. Ko nşe Samueli ni oruko ti Iya ati Baba re so o, şugbon o fi oruko ara re pamo Enikeni ti o ba wo odede Jesu yi ni lati joko si koro kan nwon ko gbodo joko ki nwon koju si, nwon ko gbodo joko ki won wo oju re tabi ki won ma so lowo, so lese.

Nigbati o şe, o ni ki nwon 'lo gbe amuku oti waini wa fun. Emi gegebi oniwe Irohin bere lowo re pe, bawo ni o şe ko Siga, nigbati o je enyin papa mu Oti.

Nigati o di ojo keji awon Oniwe Irohin si gun lo ka Jesu Ibadan mole, Ohun ti a şe akiyesi pe ko fe ni wipe, ki a ma bere oro lowo re wipe ba yio ni nkan ba yi şe je bayi, okorira iru nkan be ko si ni iye igba ti o nşepe fun awon oniwe irohin şugbon ko si enitı o şe amudi mo ninu won, nitoripe ko ri aye fi epe re ba enu.

**MOGBAYI BABY MIXTURE**
OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO




MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ta şe ni asepe fun awon Omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon işe ribi ribi ti ó ti nşe.

MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to, dara fun igbona iko, otutu, A i p e r i, Osi inu Omode, jedi jedi, kokoro ori o m o d e. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu ki omode ma nsun fonfon, o nmu ki ehin hihu je iro run fun awon omode ati njeki awon omode tobi, ati nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku alojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon omode. I s a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo re.

Igo kekere re je 2/6d   Igo nla je 4/6d
**LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo**

*Wholesale Distributors*
**A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS**

| | |
|---|---|
| 6, Balogun street, West | 34, Docemo Street |
| Lagos Nigeria | Lagos |
| Phone 22515 | Phone 24247 |

## Ijogbon fe be sile ni ogba Reluwe, o g o f a lelegberun Osise n nwon fe da duro.

### OKE MARUNDILADOJE PONUN LO WOLE NINU OWO RELUWE, PANTIWA

Ijogbon nla kan ni a gbo wipe, o ngbaradı lati be sile ni Ogba Reluwe, nipa d i d a ogunlogo awon Osişe duro lenu işe onje ojo nwon. Ki nwon ba le ri owo fi di ogidinleje owo ti o dinku ninu işe na,

O to iwon odun kan sehin n i s i s i y i ti a gbo wipe awon Olotu ile işe Reluwe şe ipinnu lati da awon enia na duro lenu işe, şugbon Ijoba Alapapose tete tese bo oro na, wipe ki nwon si da ipinnu na duro, titi ti Ogbeni Elias yio fi şe itopinpin oro na pari.

Laipe yi ni a gbo wipe iwe kan j a d e, ninu eyiti Ijoba Alapapose je Ohen si ohun ti Igbimo Reluweti şe ipinnu lati ma da awon Osişe na duro.

Nigbana ni Akowe Igbimo R e l u w e Ogbeni P. A. Carbines fi iwe sode lati odo Ogbeni Dokita Ikejiani, si odo awon asiwaju awon Osişe kakiri wipe ki won ba on şe ipade nibi kan, ki won jijo jiroro, i r u ona ti o ye, ti o si d a r a ti n w o n le gba fi din awon Osise

# Ajegboro dagba Nki Nyin O!

MO KI ENYIN ỌKAWE Irohin Imọlẹ Jakejado ilẹ Naijiria, Ẹ ku owurọ o, ẹ o jire bi? Mo tun de bi mo ti ṣe de, ṣe mo ti ṣe ileri fun ẹnyin ọnkawe Irohin Imọlẹ wipe emi ki yio fi yin silẹ lọsẹ kan lai ma fun yin ni ọrọ iṣiti tabi imọran.

Emi Ọkunrin mẹta, Emi ọmọ ti iya fi ọja pọn Emi ogboju le ogun kan ọmọ Ajẹ niko, Emi ọmọ abinu fi ọbẹ to dun jẹun yo Mo tun de o!

ẸNYIN ỌMỌ ILE ẸKỌ, Ẹ MURA SI IWE YIN Ẹ FI AIYE JIJẸ SILẸ

## Lati Owo:- LATIFU BABALOLA

Ọrọ mi ti ọsẹ yi yio jẹ lori awọn ọmọde l'ọkunrin lẹ kan si. Ẹnyin ọ m ọ d e, m u r a si iwe y i n, ẹsi fi aiye jijẹ silẹ. Iwọ ti o sọ pe o nlo si ile ẹkọ nitoripe Baba rẹ ti ni owo ti wọn ranẹ lọ si'le ẹkọ, t a b i iwọ ti wọn fi si ile ikọṣẹ ti o ṣe ọmọ jaiye jaiye kiri, ti o ko lọ ibiṣẹ tabi ile ẹkọ dede, Iwọ ni wọn yio ri nibi igbeyawo ni ọjọ isinmi, ọjọ alaruba ibi ikomọ ni itafaji ọjọ Satide ni ile ijo (West End Colliseum) ni o p o p o Apẹngbọn ti o nṣe ọmọ jaiye-jaiye kiri ti o ko fi oju si iwe tabi iṣẹ rẹ, o fi owurọ rẹ sire nuni, ranti ọrọ yoruba kan ti o sọ bayi pe:- Mura si iṣẹ ọrẹ mi, iṣẹ ni a fi di ẹni giga, bi ako ba ri ẹni fi ẹhin ti bi ọlẹ la ri bi a ko ba ri ẹni gbe okan le a tera mọ iṣẹ ẹni, emi yio duro bayi ko si aye fun mi lati kọ tan, ṣugbọn mo lero wipe gbogbo yin ni ẹ o ti ma ba mi ka lọ, ti ẹ si ti mọ, Iwọ to pe ara rẹ ni ọmọ Jaiye-jaiye, ti o ri ẹni ran ẹ lọ si ile ẹkọ ti o ko lọ, Ha! iya mbọ wa jẹ ọ, o ya lọ jawọ ninu aiye jijẹ nisisiyi ki o ya mura si iwe rẹ, Iwọ ti o si nkọ iṣẹ ki o yara mura si, ki o ma kọ ni abọ, ki o ko nigbati o yi wa ni ewe ki o ma fi agbalagba arugbo ara kọ. Iwọ ti o ri ẹni ran ẹ lọ si ile ẹkọ giga, ti o jẹ pe odidi ọdun mẹta ni o nlo ni iwe kẹjọ (form 2) ti o ko lọ ronu p wada ti o si nsọ wipe baba mi kuku ti niowo ti ni owo, o ko ranti owe yoruba kan ti o sọ bayi pe "A gbe oju le ogun fi ara rẹ fun osi ta" bi o gbe ọkan le ogun o mbọ wa tẹ, ṣe o yi ri owo baba re ko, o fi nṣe ọmọ jaiye-j a i y e ọjọ kan mbọ ti o ko ni ri ko mọ, iwọ ti o si njale kiri tabi iwọ ti o yi iwe ni ile ifi owo pamọ si ti wọn ni ko lọ gba ọgbọn pọn ti o si yi si ọgọrin pọun (forgery) ṣe iranti wipe ọjọ gbogbo ni ti ole. ọjọ kan ni ti olohun, ọjọ kan ni ọwọ yio ba ọ, o dọhun! o nlọ Kirikiri ni yẹn, o jẹ ya lọ jawọ ninu iwa burukụ yi ki o yara mura si iwe rẹ tabi iwọ ti o nkọ iṣẹ ko yara mura si.

Ti ẹ ba fẹ ri aṣiri awọn ọmọ miran ti wọn pe ara wọn ni ọmọ Jaiye-jade ti wọn ko si mọ iwe, ti o jẹ pe awọn ni wọn yio ko sinu ẹwu alakọwe eyiti wọn pe ni suits ni ede oyinbo, bi ẹniti o ti ka gbogbo iwe aiye tan ti o ba di ọjọ isimi ki o lọ si ibiti wọn ba ti ṣe ṣiṣẹ ni eti adugbo rẹ, iwọ yio ri wọn, won yio yio di gbagba bi ẹniti o ṣẹṣẹ de lati ilu Oyinbo, bẹni ko mọ A yatọ si B, Iwọ ṣa rọra bere lọwọ rẹ wipe kini wọn ṣe nbi yi ni ede Oyinbo, ko ṣe bi ẹniti ko gbọ yoruba, niṣe ni o ma ma wo ke bi ẹniti ko ri oke Sanmọ ri.

HA! Iwọ ti o ko mo iwe, ti o jẹ pe o ri enia ran ẹ lọ, iwo ni o ko lọ ti o si lọ ko sinu Cost bi ẹniti o ti ka gbogbo iwe aiye yi pari, o ko mọ wipe o fi ara rẹ se yeyẹ ni, o jẹ ya rẹ lọ ronu piwaba, ti o ba gbe oju le ogun o ti fi ara rẹ fun ọsi ta.

Gbogbo igba ti ko ba fi kọ iṣẹ tabi ki o joko ka iwe rẹ, ni o ti fi lọ si ile ijo tabi (Occation) ibiti wọn ti ṣe ṣiṣe tabi ki o lọ si ọdọ iyawo (girls friends) alaini ṣẹ lọwọ ti o wa obinrin kiri, on ni ọkọ Kudi ni Itafaji, on ni ọkọ Risi ni Ọdunfa, o b i n r i n ko jẹki o ri aye fi oju si iwe tabi iṣẹ rẹ. Awọn ọmọ miran ma sọ wipe kini awọn ko jaiye fun papa, boya awọn yio ku ni ọla tabi oṣu marun si igbati awọn wa yi, awọn ko mọ, ṣugbọn ki awọn ṣe ọmọ jaiye-jaiye dada ki awọn to ku.

Iru ero bayi ko dara ti o ba ro ero wipe iwọ yio ku ni ọdun meji ti o ko si ku ni ọdun mẹta, Ha! Enyin ọmọ iya mi l'ọkunrin ẹ jẹki a mu ero yi kuro ni ọkan ki a mura si Iwe wa, ki a ma ro wipe bi mo ba ku ni ọla ngo kuku Jaiye, ki wọn le mọ pe mo ti ṣe ọmọ jaiye jina, Ṣugbọn ṣe iranti wipe ti o ba mura si iwe ti o mo iwe rẹ gẹgẹbi Ọlọla wa Nnamdi Zi wọn yio ma ṣe iranti rẹ wipe ọmọ yẹn ko jẹ fi iwe rẹ sire wọn yio si ma fi ẹ ṣe apejuwe pe Ọlọrun jẹki ọmọ mi mo we rẹ bi lagbaja, o fẹran iwe rẹ ju onjẹ lọ.

IYOKU DI ỌSẸ TOMBỌ

## Ikilo fun gbogbo Enia

Awa Olotu ati Alabojuto iwe Irohin Imọlẹ ti Eko, fi iwe yi se iṣi leti ati ikilọ fun gbogbo awọn Aṣoju wa wipe, ỌGBẸNI ỌLATUNJI AKINDURO ti o ngbe NO. 142, STRACHAN STREET ni EBUTE-METTA, ti o si ti nṣe iṣe oniwe Irohin lọdọ wa, (iwe Irohin Imọlẹ) ti ṣe aṣemaṣe lẹnu iṣẹ, a si ti da a duro ti ohunkohun kan ko si pa awa pẹlu rẹ pọ mọ.

Nitorina, ẹnikẹni ti o ba wa fi o r u k ọ wa gba owo tabi ohun kan lọdọ rẹ, ẹ maṣe gba, ṣugbọn ẹniti o ba lọ ko sinu p a k u t e rẹ, ko kan wa, Oluwa rẹ fi owo rẹ jọna nuni.

**Awa ni**

*OLOTU IROHIN IMOLE*




# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

## AWON KOKORO ATERE GBOJIKAN NILE KENYA

KENYA:- A gbo irohin wipe, iru awon kokoro kan ti nwon gbojikan nile Naijiria ninu odun 1946 ti nwon npe ni kokoro Atere. Dudu ni awon kokoro nwonyi, nwon si kere ju kokoro Mobimoni lo. Awon kokoro Atere nwonyi buru die ju awon esu le, nitoripe, esu ko nje Paki tabi gbaguda sugbon atere nje Ireke, Ewa, Awuje, Isu, paki ati agbado. ise buruku ni awon kokoro yi nse.

Awon ero oko ti o nlo si ilu Nairobi ninu Reluwe ati awon ti o mbo lati Mombasa ko le te si iwaju, nitoripe awon kokoro nwonyi po tobe ge bi oko ba wipe ki on ma tesiwaju, o ni lati ye kuro loju irin nitori awon kokoro na boju ona oko mole, fun iwon ibuso metadilogun ese ya ju moto lo ni. Kokoro Atere yi bo oju ona reluwe mole tobe ge ti o fi je pe wakati merinle logun ni oko ile fi nrin ogoin ibuso. Enyin Alufa, ojise Olorun enyin Aladura, ati enyin alufa Imale e ba wa bo Olorun Olodumare, ki o mase jeki kokoro Atere yi tun pada si odo wa mo.

## OLOPA FI ESUN MOKANLELOGOJI SUN AKOWE KAN NI ABEOKUTA

ABEOKUTA:- Okunrin kan ti o nse isiro owo fun Ogbeni Odulate, Olotu Alabukun Patent Medicine Store, ti nwon npe oruko re ni Ganiyu Okewale, ni a gbo wipe awon Olopa mu ti nwon si fi sun esun mokanlelogoji ti o je ti Ole, o yi iwe pada, o si jale owo bi poundinlogorun ninu owo Oga re.

A gbo wipe larin ojo kedogun osu keta ati ojo ketadilogun osu kerin odun yi ni Ganiyu Okewale se aiyederu oruko Oga re sinu iwe owo, o fi gba ogbon poun kan, o tun fi omitan gba ogun poun, gbogbo owo ti o gba je mejindinlogorun poun. (£96.)

Okewale tun gboju gbaiya, o tun lu wayo ati jibiti fun akowe owo ti o wa ni National Bank. Adajo bere lowo Ganiyi Odaran na wipe, o jebi, tabi o ko jebi o si dahun beni on jebi. Adajo ni bi awon Olopa ba ri enia ti o le fi owo si iwe igba ponun niki nwon to gba iduro re. Adajo so igbejo di ojo Alamisi ti ose ojo kerin osu karun odun yi (4th May 1961

# OLOFOFO

Lati Owo:- Omo ADE

O BERE LATI LOJU EWE KEJI

Sebi enyin ngba lagba ni e mu mu awon omode ti nfa won bodi ti won ma ngba owo lbole fun yin ti won ba si fi asiri wonyi han won tan nwon a si mo ju enyin paapa le, nitorina ni mo se so pe enyin ni o ba aiye je. Ona keji ewe, enyin na ni e fi ona bi ati ni lati ma gba owo lowo enikeni ti yio ba wo ise han ki o to le wo ise, nitoripe nigbati e gba owo lowo omo ti tele yin ti o si tun fe gba elomiran ti o si fi han bayi pe ayafi ti e ba gba owo lowo re ki o to le wo ise dajudaju omo ti o tele o ti ri alebu re dandan on na si gbodo se be bi ipo na ba de owo re.

Laipeyi enikeni ti o si nwa ise ti a gba owo lowo re ki o to wo ise dabi eniti o si Sobu lo ra oja ti oni sobu na kowe ase lati gba ohun ti o ra pado lowo.

Nitorina enikan ti nwa ise ti a si gba owo lowo re ki o towo ise ti ra ibi se re na pa niyen eyi lo nfa ti omo se ma ri opolopo Oga ilese fin ti oga ko fi je enia pataki loju re mo. O tile ye ki n bere re lowo enyin ti e ngbawo na pe kini ohun rere ti e nfi owo na se? nitoripe eni Olofofo rope eyi yi nda gbese si yin lorun si ni, o ngbe koto buruku siwaju yin ati oruko buruku lehin ola.

Nitorina mo kesi gbogbo enyin ti e ngbawo ki e to se iranlowo ki e to gba enia sibi ise mo fe ki e jowo kuro ninu iwa be nitori ko si esan rere ti o le jade lati inu re wa.

## Ewa wo Ere Aladun

ARI MA LE LO, AWO PADA SEHIN.

### EGBE ARIKEWUYO Omo ilu Ilala (Lagos Branch).

Awa egbe ti oruko wa wa loke iwe yi fi tayotayo pe enikeni lati wa wo ere MOLIKI GBUGBU ELERE EGUN, ere ti yio se yi je akoko ti ko ti se iru re ri ni Eko nibi yi.

A pe enikeni lati wa fi tayotayo wa wo ere na ni ojo ale aisun odun Ileya ti se ojo kerindinlogbon osu karun odun yi. (26:5:61)

Ibiti a o ti se ere na niyi:- No 82, LEWIS STREET LAGOS. Lona Obalende ni Eko. Ere na yio bere ni dede agogo mejo ale titi di agogo merin oru moju ojo keji (From 8p.m - 4a. m.) Irohin ko to afojuba ni ere na. eniti o ba ri lo le so.

Owo Iwole bere lati Sile Marun, ati Sile Meta, (3/- and 5/- Flat ). Ere na yio ju iye ti e fi wole lo. A ki gbogbo awon Odomokunrin ati Odomobinrin ati gbogbo awon Agbalagba, Oluwa jeki ojo na ba wa laiye pelu Alafia Ara. Amin E ku ipalemo Odun Ileya na.

Eyi ni Ibiti e o ti ma ri Tiketi (tickets) wa ra:-

1. D. Babalola No. 69. Glover Street Lagos.
2. Yakubu Alabi No. 6. Inasa Court, Lagos.
3. Jimoh Ayanda & Brothers, 60, L. E. D. B Shop, Idunmagbo Avenue, Lagos.
4. Y. K. Alabi No. 1 Reclamation RD. Lagos Naijiria.

AGED MEN MUST TAKE

## SENGOVAN

*EXTRA STRONG FOR VITALITY AND ENREGY*

**Immediate Result**

Sengovan is the most valuable product known all over the world since many years and used by all men who look for New Life.

Sengovan is based on latest scientific experiences. It is a pharmac composition of male Germo-Glands and Hypophysis Cerebi together with an exactly dose of Lecithine and some other efficacious substances of high quality.

Sengovan is a remarkable remedy whichgives marvelous result within half an hour after use.

**That is the great advantage against all other similar rejuvenation cures.**

It is a harmless but most efficacious preparation against sexual weakness, sterility and impotence against nervours troubles and loss of youth and energy.

Sengovan gives marvellous results and—most important fact not only marvellous, but almost immediate result in all cases of Sterility, Sexual Exhaustion and Importance. Again Sengovan is a most valuable nerve-tonic.

At the same time Sengovan is free from poison.-

Sengovan may be used without any fear of unpleasant consequences enslavement to habit.-

DIRECTION 1 to 2 Pills to be teken half an hour before result is wanted. Try whether 1 only pill is sufficient for your constitution, if so do not take more pills at one time.

**Imported and sold by :**

HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES

Phone 23745 26, Bishop Street

LAGOS.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16 Bamgbose Street Lagos Phone: 21985 Oloto. E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street Surulere, YABA.